**3.** Nitorina mã şe àfọ̀mọ pẹlu ọpẹ didu fun Oluwa rẹ ki o si mã tọrọ idariji lọwọ Rẹ̀. Dajudaju Onjẹ Olugba-ironupiwada.

فَسَبِّحْ بِحَمْدِ رَبِّكَ وَاسْتَغْفِرْهُ إِنَّهُ كَانَ تَوَّابًا ﴿٣﴾

## *(111) Suratul Masadi*

سُورَةُ المَسَد

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Ọwọ Abi-Lahabi (baba ina) mejẽji ti şofò, o (on na) si şofò.

تَبَّتْ يَدَا أَبِي لَهَبٍ وَتَبَّ ﴿١﴾

**2.** Awọn Ọrọ̀ (owó) rẹ̀ ati işẹ ti o şe kò ni şe e ni õre kan.

مَا أَغْنَىٰ عَنْهُ مَالُهُ وَمَا كَسَبَ ﴿٢﴾

**3.** Yio wọ ina jijo fofo.

سَيَصْلَىٰ نَارًا ذَاتَ لَهَبٍ ﴿٣﴾

**4.** Ati iyawo rẹ̀ a-ru igi işẹpẹ ẹlẹgun.

وَامْرَأَتُهُ حَمَّالَةَ الْحَطَبِ ﴿٤﴾

**5.** Ti o si ni okun lílọ́ (masad) lọrùn.

فِي جِيدِهَا حَبْلٌ مِنْ مَسَدٍ ﴿٥﴾

## *(112) Suratul - Ikhlãsi*

سُورَةُ الإِخْلَاص

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Sọpe: on ni Ọlọhun Ọkan-şoşo.

قُلْ هُوَ اللَّهُ أَحَدٌ ﴿١﴾

**2.** Ọlọhun ni Ọba ti a ma nronu kan.

اللَّهُ الصَّمَدُ ﴿٢﴾

**3.** Kò bi ọmọ bẹ si ni a kò bi I.

لَمْ يَلِدْ وَلَمْ يُولَدْ ﴿٣﴾

**4.** Bẹ si ni kò si ẹnikan ti o jọ Ọ.

وَلَمْ يَكُنْ لَهُ كُفُوًا أَحَدٌ ﴿٤﴾